**Owe**

KITA-KITA OMO TI ARI IKI, KI A ŞIŞE BI ERU KO DA NTAN

# ELETI OFE

A-NJU-WON-KO ŞE WI LEJO

**Asoje**

ENIA BI IYA KOSI TANI JE Ş'ỌMỌ ỌLỌMỌ LORE

VOL. XIII No 101 LAGOS. SATURDAY AUGUST 12, - AUGUST 18, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# JAMBA OKO OFURUFU SELE, OMO ILEWE ATI OLUKO SOFO EMI

OSLO - Nigbati awọn ri ajoṣa-ku-silẹ ọkọ ofurufu ti awọn Oyinbo Gẹsi kan ti awọn ọmọ ilewe mẹrin-le-lọgbọn, Oluko meji ati awọn oşiṣẹ inu ọkọ na mẹta ti o kuro nilu London lọjọ Alaruba (Wednesday) lori Oke giga ti o to bi ẹgbẹsan ẹsẹ kan nitori Stavanger nilu Norway.

Awọn ọlọpa ro wipe ko daju pe eni kan le wa laye ninu rẹ nitoripe bi ọkọ na ti ja lulẹ l'o gbina. Nwon so wipe nwon gburo oko ofurufu na ni nkan bi işẹju meje ki o to gunlẹ si ibudo ọkọ Ofurufu ni Sola nitosi Stavanger.

Awọn ọmọ ilewe na ti ntọju owo won lati lati fi sanwo oko ofurufu na lọ lo isinmi won. A si gbo wipe awon haya ọkọ na lọwọ awọn ẹgbẹ Oniṣowo kan ni aşiri. Awon ti nwon wa ọkọ yi sọ wipe o dabi ẹnipe ọkọ na f'ori sọ ẹgbẹ oke, o si tun lọ soke si ki o to lọ jaluịẹ son oke giga na.

Lọwọ jamba ọkọ ofurufu Oluwa rere gba wa.

## Oloye Akintola Gba Igbimo Ibadan Ni Imoran

IBADAN -- Olotu ijọba ipinlẹ Iwọ-oorun ati Igbakeji Aşiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) so ninu iọ re ti o fi ki awon Olugbimọ (Councillors) ku rire wipe o dara fun awọn adibo ti o dibo fun igbimọ ibilẹ ilu Ibadan lori wipe nwon mọ riri ẹ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre nşe, eyi si han nipa atilẹhin ti nwọn ṣe fun ẹgbẹ na ninu ibo igbimọ ibilẹ ti a di kọja yi.



Olotu ijọba sọ wipe, laişiyo-meji abayọri ibo na fihan wipe nwọn ko ni igbẹkẹle si ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C) mọ ati awọn alabaşepọ wọn. Ko si ohun ti o ye awọn obilẹjẹ si ọna ajumoşepọ ati pataki si Ijọba ipinlẹ Iwọ-orun ju eyiti awọn adibo şe fun ẹgbẹ N.C.N.C yẹn lọ. Gbogbo awawi ti awọn tun nwi, jẹ arowo ẹnu lasan ni.

Olotu ijọba tilẹ tun pe awọn Aşiwaju alabaşepọ ẹgbẹ N.C.N.C. ti nwọn nparowo nija, Ọgbẹni R. O.

Wo yoku loju ewe kẹfa

## Nwon Fi Alakoso Ile Onje Sun Esun Apania.

xoh——hox

PORTHARCURT---Dokita Joseph Okoye, ti o nşişẹ ninu Ile Iwosan ijoba ti ilu Port Harcourt ni o sọ niwaju Adajọ Kotu Giga wipe ọta ibọn merindinlogoji ni on yọ lara obinrin kan, Ibinnga Azuma ti awọn yinbon pa nigbati on şe ayẹwo ara obinrin na.

Dokita yi njẹri fun ijọba lori esun ipania ti awon fi ara ilu Okirika ti o nşe Alakoso ile onje kan, Theophilus Kalio sun, Dokita Okoye sọ wipe on ni igbagbọ pe ọpọlọpọ ibon ni awon yin fun obinrin na.

Awon alafisun sọ wipe Kalio pa obinrin na ni asiko ijagboro ilu Okirika ninu oşu April ọdun tokọja.

Adajọ fi gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kerinla oşu August, 1961.

# OWO TUN TE ADAMODI DOKITA M'RAN

IDOMA - Ko ti p' harmo a oko l'enu ti ilu Agatu ni agbegbe ilu Idoma nigbati awon olopa ibile lo bile le ti ju ilaisan ti Dokita adamodi ti oruko re nje Jacob B. Macrae ni ilu Ariwa.

Ichin ti a ri gbo ni wipe Olutoju awon alaisan ati awon ... ti o ... salo nigbati nwon gbo pe owo awon olopa ti te iranbi Dokita na. Nigbati awon olopa mu Dokita yen ye na, idamu de ba, o si fi po un meji se etutu fun olopa.

Esun ti a ... sun ri wipe Jacob Macrae ti ko gbawe eri imo nipa cogun, ngun awon l'abere o si pe ara re ni Dokita alata, Onidajo Kotu sa konko ewon osu mefa mo lara.

Awon olopa tun ase iwadi moto kan ti adamodi Dokita ra nlo, ti ki nse oruko re ni nwon fi gba ... ase fun moto na. Oruko ena ti o wa ni Ebute Metta, l'Eko, ni o wa ninu iwe ase moto na.

---

# NWON RO OLOYE IJESHA MEJI L'OYE

ILESHA - Irohin kan wa wipe Oba A. O. Bilada Keta, Owa ilu Ijesha, ti kede rire - l'oye ti awon meji, Oloye Ojo, gegebi Sokoti adugbo Egbedi ati Oloye Olowoteere gegebi Ayalodi ti adugbo Ijoka ninu Ilesha.

Ikede na ti o jade ninu iwe Ikede ti Ijoba tun fi kun wipe Oba Bilada tun ti da Oloye Ojimi duro gegebi Eminiwa adugbo Egbeidi ninu Ilesha pelu.

---


Don't waste water



E mase fi omi sofo


ORO OLOTU.

# Ohun iyanu ko ni tan laiye

Sugbon nibo ni aiye wa yi nlo? opolopo iyanu ati orujeje ni awon ijoba alagbara udawole ni aiye wa isisiyi ti nwon si nse ni aseyori.

Okan pataki julo ti o ya enia lenu ni lati gbo wipe awon ijoba ilu Rosia ti fi enia meji ranse lo si sanmo keji ninu oko Ofurufu ti awon mejeji si pada wa gunle sile aiye ati si agbegbe ilu won ni alafia lehin nti oko Ofurufu won ti gbe won yi ile aiye po lera-lera.

A ri wipe gbogbo nkan wonyi dara nitoripe o nmu imo ilosiwaju wa sugbon amoju nkan ko ma nfi gbogbo igba sunwon, eyi ni eru okan fi nba wa ti a fi s'abere wipe nibo ni aiye wa isisiyi nlo o?

Oro re o, enyin enia wa.

---

# ORE KII GBE

Lati owo :- MOSES FEMI AKINBODE. ONDO

Ni akoko kan, obinrin kan wa, ni ojo kan Obinrin yi lo si inu igbo lati lo wa igi ti yio fi dana.

Bi o ti nlo' o de abe igi kan, o wa ri awon omo ekun meji, O sure mo won pelu iberu, gege bi o ti mo wipe ti enia ba ri ekun, eru akoko ba oluware na. Sugbon obinrin yi so iberu re nu, o si ye won wo nitori ewa won po gidigidi. Lehin eyi o rora gbe won si aye ibi ti o ti gbe won pada. O si ba ona tire lo.

Nigbati o te, obinrin yi ma nwa si inu igbo lati ma gbe onje fun awon omo ekun mejeji yi. Sugbon bi o nti se eyi ni awon elomiran ma nbuu won a si ma so wipe o nsiwere ni. Sugbon obinrin yi sa koju si tire, ko si da won lohun.

Bi obinrin yi ti nwa sinu igbo yi, ni baba awon ekun meji yi sa amo, ti o si nwo gbogbo nkan ti obinrin yi nse fun awon omo re. Lehin osu melo kan obinrin yi bi omo kan, Ni ale ojo na, baba awon ekun yi pa eranko nla kan ninu igbo, o si gbe wa si enu ona obinrin yi.

Nigbati ile mo, obinrin na ri ese baba awon ekun yi ni enu ona re, o si ranti ohun ti o ti fun awon omo ekun na.

Itan yi ko wa wipe ki a ma se ore ki a si mase wo rkan ti awon enia buburu nso.

# IJỌGBON ILE KONGO TI D'ERO.

Leopoldville- Lehin ti fun ṣi Ile Igbimọ ile Kongo, ti nwọn yan Ọgbẹni Cyrille Adoula ni Olotu ijọba, ti gbogbo rogbodiyan ilu na rọlẹ patapata, ni Olotu ijọba titun ti ilu Kongo sọ wipe on yio fi ọwọ gbigbona mu ilu Katanga ti o yapa lọ bi Alakoso ijọba ilu na ko ba ronu pivada, ki o fi ara mọ ijọba titun.

Ni ọjọ keta ti gbolohun yi jade lẹnu Olotu ijọba Ọgbẹni Cyrille Adoula, ni Ọgbẹni Moise TShombe ti iṣe Alakoso ijọba Katanga ti o ti iṣe ori ikun yara fa ọkọ rẹ si itọ, ti o nwa aye lati tete pari ede-aiyede na, o si sọ wipe on yio fi awọn isọgbe or ranse si igbimọ ijọba nla ti Kongo ki nwọn wa f'arami ijọba ati pe ki nwọn lẹ pari gbogbo aọ won.

Awọn Olugbimọ ti p'inu lati ko igbimọ kuro nibi ti nwọn gbe ṣe pade akoko kẹhin nkan ti oṣu mẹfa ti ida udapọ ti kere, ki nwọn lọ maa ṣe ipade wọn ni Leopoldville ti o jẹ olu ilu Kongo.

---

**Iwe Irohin wa ladun pupo**

---


*Mimoṣe owo lao fi mõ!*

Ẹnito lè ṣiṣẹ owọ

ni yio mã gbowo to dara.

*O lé ni ẽdẹgbẹta ara Nigeria*

ti a ti kọ́ nisẹ owọ tabi ti asi

nkọ́ nisẹ ni awọn ile ikọ́ṣe lọdọ

**THE UNITED AFRICA COMPANY**

THE UNITED AFRICA COMPANY

OF NIGERIA LIMITED


# KONI KU IKU ORO MO

---

EKO -- Idajọ iku iyegimọ-kan ti Kotu Azizi da le Shitta Ọlagunju lori fun ẹsun apania ti nwọn fi sun lori iku Egungun Gbangbose ni odun to kọja ni Ọjọla nla Adele Gomina Gbogbo-gbo ti fi ọja-aru wo oro na, o si yipeda si wipe ki o sa ẹwọn ni gbogbo ọjọ aiye rẹ.

Nipa iwe ijọba ti nwọn ṣe ni ọjọ Jimọ (Friday) ore to kọ'a ni nwọn ti sọ Adele Gomina ti gba imọran Alaṣẹ Aabo ijọba ati Igbimọ awọn Olubajiroro ijọba Apapọ ti nwọn sọ pe ki o fi ojo-anu wo idajọ na, o si yipada si ẹwọn gbere fun Shitta Ọlagunju.

---

### Enito Woko Ofurufu Lo Silu Osupa Gunle Saiye Lalafia

MOSCOW - Ọga Ologun Major Gherman Titov ti awọn Ijoba ilu Russia fi sinu ọkọ ofurufu lọ silu Oṣupa, sanmọ keji, ni a gbọ wipe o pada de sile aiye, ni ọjọ kẹfa oṣu yi, ti pe ọkọ rẹ pada gunlẹ si agbegbe Saratov, nibi ti ibuso bi adota-le-nirinwo si ilu Moscow.

Ọmọ odun mẹrin-din-logbon ọga'gun Mẹjo yi ti yi aiye po ni ẹmẹta-din-logun larin wakati mẹdogbon ki o to pada gunlẹ Irohin wakati mẹdogbun ati iṣẹju mejidin-logun ti o lo ki o to pada wa sile aiye

( Wo yoku loju ewe kẹrin )

# KEKE ALUPUPU OLOGERE OLOJU-MEJI



EWO odomobinrin ti o mu Keke Ologere Alupupu re dani pelu oju atupa ele nla meji ti imole re ko legbe ti nwon ba tan ni oru, o si le rin Adorin itusọ ni wakati kan.

## Egbe Afenifere Bori Ninu Idibo Ilu Ibadan

IBADAN - Ęgbę Afęnifęre (Action Group) t i o ni ijọba ipin'e Iwę-orun ni o beri gbogbo ibo igbimọ ibile mejeji ti nwọn di ni ojọ Satide to kọja.

Gbogbo ijoko ti nwon dibo fun n i n u gbogbo igbimọ ibilę na ni ęgbę Afęnifęre ko tan patapata, ayafi awọn ijoko męta pere ti awọn kofęsra moęgbę kokan ti o wọ'e pẹlu.

Ki a ma gbagbe wipe ęgbę N.C.N.C. d pomọ Mabọlajẹ ti o jẹ Ilọ Atatako ninu ijọba Iwę-oruu ti şe ikede wipe awọn ko ni ba wọn du ibo na, ati pe awọn yio yọwọ-yọsę kuro ninu a ndibo.

gbogbo awọn ọmọ ęgbę wọn ti o ti sanwo fun idibo ni owo w ọn jona nitoripe asiko ti kọja ki nwọn to sọ wpe awọn yọwọ kuro ninu ibo na.

Banna ni ęgbę Afęnifęre (A.G.) tun ko gbogbo ijoko igbimọ ibilę Iyekuselu ti ęgbę N.C.N.C. kọ lati ba wọn dibo. Enia karşoşo ti o wọle laini alatako ninu ọmọ ęgbę N.C.N.C. ti kọwe fi ijoko rę silę ninu igbimọ na.

## Nibo Ni Awon Imale Yio Ti Se Odun Nabiyu

Iwe Si Olotu,

Ę Jọwọ Olotu, Ę gba mi laye lati bawa bere ọrọ yi lọwọ awọn Igbimọ ibilę Eko ibo ni ijọba fi silę fun wa ti ao ti şe Nabiyi ni ọdun ni ? Nabiyi ra ti sun mọ tosi ako si gbọ ikan-kan, bẹni Orik tiko ti ati nşe Nabiyi n a n i ę tiifi kọ isọ f u n Ọlọja Ę Jọwọ Ę şe alaye Ibiti ao ti şe Nobiyi fun wa ni Ọdun ni o. Ki Oluwa mu dagba soke ba ilu ki anfani Ilu ba gbogbo wa o.

Mo dupę lọwọ Olotu

Emi ni

A. S. K. Mọyọ

ELETI-O F E D'ARABA ROSE FI SERE

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.
HINDU SANKARA, 421 Archway Road, London, N.6, England

## Enito Woko Ofurufu

(O bere lo ju ewe keta)

J. rohin igbadun ati iyanu, o nję u n, o si rin ninu o k o na bę l'o si tę waya oro ranşe si awon Alaşę ijoba ilu Moscow.

Eyi ki işe nkan kekere, joni loju gidigidi.

KU'JA WOLU

NIBGATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ŞE LE RA OMIRAN EYI NI OGUN TI ONI ŞOWO LE ŞE TI ỌJA RE YIO FI MA TA BI IŞU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin ELETI-OFE

**IMỌRAN FUN AWỌN EGBẸ N.P.C ILẸ IGBOMINA OKE ODDẸ ATI ỌFFA.**

Lati Ọwọ A.R.A ORILONISHE (ỌMỌ OKE ỌDDE).

O JẸ ohun itiju ulu-ni fun mi lati lero wipe enyin ọmọ ilẹ Igbomina egbabọdi fun ibo L.T.C. tokẹja lati le jo wipe ẹ nda anfani i lẹ nyin ru, ati wipe ẹ koro ẹhinwo rara, nitori wipe awọn Olomi to wa ni N.A. ILỌKIN ntiyin ni itikuti wipe awọn yio ṣe kin ni kan fun yin, ẹnyin na fi gba bẹẹ. Ha Ha! ẹ ẹfi awọn ọmọ nyin fun Ẹkun pajẹ, ẹ ma se ro bẹẹ rarao. Iru awọn akikanju ilẹ Igbomina, awọn bii HON. J.G. Ẹkunrin of OKE ỌDDE ati iru awọn bi HON. J. S. Ọ'awoyin of ỌFFA wọn ti ja fun Ilẹ Igbomina pupọ. Ejẹki a ni ifi ọwọsowọ, latile gba ara wa s'lẹ ni Ilẹ Igbomina, awọn Baba wa loma npa owe kan wipe Igbati mọi ẹiti nro aṣọ ihuriho ni iakara wa. Lati igbati ẹ ti nda owo ORI bọọ, kin ni nkan anfani ti ILỌRIN se fun wa ? ibẹ ṣa ni a nda owo ori si.

Igbati awọn ara ILỌRIN ti mọ wipe awọn ti o fẹ gbawa sile tiyẹju, on ni wọn ṣe ntan yin jẹ, ẹ jọwọ ẹnyin enia mi mọ'e yin t'ọwọ t'ọwọ ati iteriba, mo fẹ ki ẹ ranti owe awọn Baba wa ti o sọ wipe "IGBẸ ADIẸ KODARA NI MỌSALASI SUGBỌN ITAN RẸ DARA LORI IRẸSI FUN ALUFA" wọn ti mọdaju wipe awọn mejeji yi ko ni fẹ ipalara fun ilẹ wa. Ejọwọ ẹ m ṣe jeki oju twa ... k ... mọdaju wipe eyin ... wa kan sọ bayi wipe "BI INA KO BA TAN LASỌ EJẸ KII TAN LEKANNA" TO TO ... bi owe. Ero aṣe jeki o re enyin Baba wa e jeki a mura lati le bọ okun ti wọn so mowa lẹrun kuro

(Wo yoku lẹjọ ewe Ẹfa)




# AWỌN ONISE OBA ILU GHANA LO BE ILU OXFORD WO



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn onisẹ oba ti o ti ilu Ghana wa bẹ ilu Oyinbo wo fun ọsẹ mẹta pare gẹgẹ bi alejo Ile iṣẹ Ijọba Ajumọṣepọ (Commonwealth Relations Office).

Awọn Oluberewo na ni, Ọgbẹni K. A Badu, F Hall-Baidu, E. O. Boapeen, J. A. Duugan S. A. Marfo, J. Lovelace Oppong ati Omidan P. Redmayne ti o nṣe afinimọna wọn.

MERCEDES-BENZ

220



An elegant fast touring car

of technical brilliance

This is the new Mercedes-Benz 220 which takes the place of the type 219. his beautiful car is outstanding in style and equipment, in road holding and comfortable suspension.

FROM

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB) IBADAN, KANO, JOS KADUNA,

PORT HARCOURT, ABA.

SUB-DISTRIBUTORS

ARMEL'S TRANSPORT LIMITED

BENIN-CITY ONISTHA & ABA


# OLORI ILE ISE OWO ALAPAPOSE



Ogbẹni Dennis Vosper ti o ti jẹ Alabojuto fun ijọba ni ile iṣẹ Alabojuto ohun okere, ni nwọn ti yan ni Olori ile iṣẹ ọwọ alapapọse titun.

## Oloye S. L. Akintola

O bẹrẹ loju ewe kinni

A. Akinjide ati Ogbẹni Adeoye Adisa wipe bi o ba da wọn loju wipe awọn ọpọlọpọ enia wa pẹlu wọn nilu Ibadan, pe ki awọn kọwe fi ijoko wọn sile ninu ile igbimọ ki wọn tun dauraawo Olotu ijọba sọ wipe on yio fun ẹnikọkan wọn ni ẹdẹgbẹta ponun (£500) fun inawo owo idibo wọn.

KO HA TA BI?

Ni ipari rẹ, Olotu ijọba ki awọn ti o wọle ku ẹ̀ re, ... wọn ... wipe ẹru ti o wuwo ni awọn gbe ... ṣe is, wọn de'po ti ẹnikẹni yio ... wọn ṣe ... .

## Ile L'abọ ... simi Oko

A... fun Ijọba ile Nigeria nilu Ghana, Oloye Kolawole Balogun yio pada wale ni ojo Tuesday ... ti ṣe ojo kedogun oṣu August, 1961, ... Parki ni Ghana fun ... mo-... .

..., Oloye Balogun yio rin yika ile Ghana lati ... fun awon omo ile Nigeria ti o wa nile Ghana. ... Oloye Balogun yio se gbeh... ni Ghana ni ojo Monday ... Nigeria fi ta Ile ... Ologbe George Padmore lore ti yio ... .

IMỌRAN FUN AWỌN ẸGBẸ N.P.C ILẸ IGBOMINA OKE ODDẸ ATI ỌFFA.

Lati Ọwọ A.R.A ORILONISHE (Ọ... OKE ỌDDE).

(O ... loju ... katun)

Mofe ki e ṣe akiyesi awon ilu ti mo fe daruko wonyi, 1. OKE Ọ DE 2. I... BAJA 3. ... 4 ESIE 5. ỌFFA 6. E...ITI 7. ILE ISIN. 8. OMUPỌ. 9. OMU ARAN O kan awon ilu tee ... afi ẹgbẹ ... lakaiye yanju ... Igbomina, o yẹ o si tọ ... le fi ... awọn Ẹgbẹ Igbomina Parapọ, ki ... kuro lọwọ awọn ... ẹgbẹ N.P.C. ... ki a le di Ominira ... wa, tiko si ni si iyọnu fun ẹnikẹni wa. Oluwa yio gbawa lọwọ Amunu Ṣika Modeṣoto amin Oluwa Olodumare Baba alanu yio kowa yọ lọwọ awọn Ọta wa o. Ẹo tun ... irohin yoku ni ọsẹ tombọ.

Odigba ọsẹ o.

Ipade wa bi oyin o.

**E ma ka iwe irohin Eleti-ofe Losose**

... by the ... Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370.